Bibeli fun awon omode

# Olorun bu ola fun Josefu eru



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: M. Maillot; Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: M. Maillot; Sarah S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Ona aito ni a gba fi Josefu si ewon lati odo Potifari, Oluwa re. Ninu tubu, Josefu gboran o si je oluranlowo. Oluso ile tubu gbekele Josefu fun itoju tubu naa. Nitori pe Olorun wa pelu re, ile tubu naa di ibi ti o dun un gbe fun gbogbo awon elewon.



Agboti ati alase oba wa ni tubu. Josefu bi won leere lojo kan, “Ki lo de ti inu yin fi baje?” Won dahun wipe “Ko si eni ti o le tumo ala wa fun wa.” Josefu wi pe “Olorun le se. E so ala yin fun mi”.



Josefu so fun agboti pe, “Itumo ala re nipe ni ojo meta loni, oba Farao yoo se ojurere fun o. Ranti mi ki o si so fun Farao lati yonda mi.” Itumoala ti alase ko dara. Josefu wi fun un pe, “Iwo yoo ku ni ojo meta oni.” Ala mejeeji wa si imuse.



Sugbon agboti gbagbe Josefu, a fi ojo ti Farao naa ni iyonu nipa ala ti o la. Farao wipe “Mo la ala kan.” Ko si enikan ninu awon amoye re ti o le fi itumo ala re fun.





Nigba naa ni agboti ranti Josefu ninu tubu. O so fun Farao nipa re.

Logan ni Farao ranse si Josefu. "Ala re je ise lati odo Olorun" eyi ni esi ti Josefu funoba. "Ijipiti yoo ni odun meje opo leyin naa odun meje oda ti o lagbara."



Josefu w agba oba ni imoran bayi, “Se eto lati ko ounje pamo ni odun meje opo yii, bi beeko, ebi yoo pa awon eniyan re ku ni akoko iyan”. Fara oba kede wipe “Olorun wa pelu re, iwo ni yoo se akoso ni Ijipiti, oo si je igbakeji mi”.



Odun meje opo de. Leyin naa odun meje iyan. Ko si ounje nibi gbogbo ayafi ni Ijipiti nibi ti won ti ko opo ounje pamo. Ni ilu Josefu, iyan mu awon ebi re, ebi si n pa won.



Awon eniyan lati orile-ede gbogbo n lo si Ijipiti lati ra ounje. Jakobu pase fun awon omo re, “E gbodo lo ra ounje ni Ijipiti, bi beeko, ebi yoo pa wa ku.” Nigba ti won de Ijipiti, awon omo re mura lati ra ounje.



Awon omo Jakobu teriba fun eni ti a fi se alakoso ni Ijipiti.  Won ko mo Josefu arakunrin won mo. Sugbon Josefu mo won.  Josefu ranti ala igba ewe re.  Olorun ti gbe e ga ju awon arakunrin re lo.




Josefu se ologbon pupo. O soro sakasaka o si fi Simoni, okan ninu awon arakunrin re pamo. O wi fun awon arakunrin re yooku pe, “E gba ounje, e lo sile ki e si pada wa pelu abikeyin yin.

Nigba naa, ni ma mo boya e ki se ami."
Awon arakunrin re ro pe boya Olorun
n fi iya je awon tori pe a
won ta Josefu bi eru
lodun die seyin.



Oro naa toju suJakobu ati awon omo re. “A da owo wa pada pelu ounje. Alakoso naa si wi pe a gbodo mu Benjamini wa.” Jakobuko lati je ki Benjamini lo. Ko pe ti ounje fi tan. Awon arakunrin yii ni lati pada lo si Ijipiti. Benjamini bawon lo.



Nigba ti Josefu ri Benjamini o pase pe ki awon iranse re se ase nla. A pe awon arakunrin re sibe. O bi awon arakunrin re leere pe, “Se baba yin n be ni alaafia?” O le ma ro bi yio se ko gbogbo ebi papo.



Josefu fe mo boya awon arakunrin ronu piwada lori ese ti won ti da lodun die seyin.  Leyin asenaa, o fi ole lo won.  O wipe, “Lati fi iya je yin, maa mu Benjamini sile gege bi eru mi.”  Juda bere si nii bebe pe, “Oluwa mi,



dipo ki o mu omokunrin yi sile, kuku gba emi.” Josefu mo pe Juda ti o damoran ki a ta oun o ti yipada nitooto.



Nigbati Josefu ko le fi ife to ni si idile re pamo mo, o ni ki gbogbo awon ara Ijipiti jade. O si bere si sokun. O wipe, “Emi ni Josefu arakunrin yin, eni ti e ta si Ijipiti.” Awon arakunrin re ko le fohun nitori ti oro naa ya won lenu, eru si ba won.

Josefu mu awon arakunrin re ni okan le.

O wipe, “Olorun ti gbe mi ga ni Ijipiti ki n ba le gba emi yin la ninu iyan yii. E lo mu baba mi wa. Maa bojuto yin.”





Jakobu ati
Josefu tun pade ni
Ijipiti gbogbo idile
won si n gbe ni
alaafia ati ninu opo.

Olorun bu ola fun Josefu eru

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Genesisi ori kookandinlogoji de ori karundinlaadota

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.